# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 860 LAGOS SARTUDAY MARCH 16th—MARCH 2?th 1963 KOBỌ MEJI (2D)


# Sardauna Gba Iwe Ojo Iku Lowo Awon Janduku Ni Kaduna

KADUNA — Awọn janduku kan ti nwọn mbẹ l'Oke Ọya ti kọwe si Ọlọla Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto, tiṣe alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa wipe awọn fẹ pa a ninu oṣu ti a wa yi ki o mura awọn silẹ.

Irohin ti a gbọ lati Kaduna nipa ọrọ ịna ni wipe ni owurọ ọjọ kan lẹhin igbati Sardauna ti Mẹka ti o da kan lọ lati se kunkari ni o ba ri iwe yi gba nibi isẹ rẹ. Nigbati o tu iwe na wo ikilọ bi awọn yio ti pa a ni o ba' nibẹ.

Ni ijẹta ni Sardauna paapa sọ ọrọ na leti awọn ti nwọn wa si ile igbimọ ni Kaduna; o ni ẹru iku ko ba on rara nitoripe on ko fi igba kan tọrọ ẹmi gigun. O ni bi on ba tilẹ ri [illegible] on, on a tete lọ ba iya ati baba on ni ọrun ni kiakia.

Gbogbo awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Ijọba Iwọ Orun Ila Orun ati Gomina-agba, Dokita Azikiwe ti kọwe si i lati ba kẹdun wipe Ọlọrun majẹ ki a rin lọjọ ti ebi npa ọna.

## Awon Olopa Mba Dokita Olegbeye Se'jo

YABA— Awọn Ọlọpa ọtẹlẹmuyẹ mu Dokita Tunji Ọlẹgbẹyẹ, olori ẹgbẹ awọn ọdọmọde ti nwọn npe orukọ wọn ni Nigeria Youth Movement ni ijẹta nwọn si ti i mọle.

Nigbati nwọn mu u lọ si iwaju adajọ ni Kotu Yaba lana ẹsun wipe awọn ri iwe Ijọba kan lọwọ rẹ ni nwọn ka si i lẹse. Nwọn bi lere bi o jẹbi tabi ko jẹbi. Dokita na dahun wipe on ko jẹbi rara.

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

An Exraodinary General Meeting of the Lagos Race Club will be held at the Members Enclosure, Race Course, on Thursday 4th April, 1963 at 5.30 p.m. Members should please note that admission will be by production of badges only.

AGENDA:

1 Revision or Amendment of Club Rules.
2 Any other business.

CHE MILLER.
Hon. Secretary.


## Oba Tapa Se Ajo Awon Ti Moto Se Lese

BIDA — Awọn enia mẹtalelogun ni moto kan se ni jamba nigbati nwọn nlọ ba wọn se eyẹ igbeyawo ni abule kan lọna ilu Bida ni a alẹ ijaruu gbogbo wọn ni wọn si ti ko lọ si ile iwosan ni Bida.



Gbara ti ọba Tapa ti o sẹṣẹ gori oye ti gbọ ro jamba moto na, nse ni on na mura ti o gba ibẹ lọ ati ile iwosan na paapa ti o lọ wo awọn enia ti moto na se ni jamba o si ba wọn kẹdun pupọ. Inu gbogbo awọn ara ilu si dun lati ri ọba wọn, Alhaji Usman Sarki, petu ajo ti o se fun awọn enia na.

## Adajo Ju Akowe Kan Sewon Ni Igbaja

IGBAJA (Lẹba Ilọrin)— Adajọ Kotu awọn Ọlọpa ni ilu Ilọrin ju awọn ọdọmọde meji ti awọn ọlọpa ko wa si iwaju rẹ pe ọkan, Samuel Sunday Ajayi tiṣe akọwe ile oja awọn Sudan Interior Mission (S I M) ni Ilọrin ti o ji ẹrọ iya-fọto (camera) ati George (eniti o ṣẹṣẹ nkọ iṣẹ oniwasu ni Theological College) ti nwọn sọ wipe o ra ọja ole si ẹwọn oṣu kọkan.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ro niwaju adajọ nipa awọn arufin mejeji na ni wipe Ajayi ji ọkan gbe ninu awọn ẹrọ iya-fọto (camera) oni pọnun mejidin logọta ti awọn Oyinbo S I M ko si ile itaja ti gba nwọn a si, o si lọ ta a fun George ni pọnun mẹdogun; pọnun marun ni iyẹn ri san ninu owo na ki ọwọ ọlọpa to tẹ wọn

Lọya ti arufin Ajayi na gba ni irọ ni George npa mọ o ko ta nkankan fun un rara. Lọya na ni ẹrọ photo ti Ajayi ra lọwọ awọn onisẹ rẹ ni o ta ni pọnun marun fun ẹnikan.

# Eleti-Ofe D'araba




Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,387,000 miles. No doubt it would have gone on if *Daimler-Benz AG* had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last just as much now as they were then, to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

MERCEDES-BENZ

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, (EB), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCURT, ABA.

SUB-DISTRIBUTORS:

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN CITY, ONITSHA, ABA.


## Dokita Kan La Odi Lohun

MOSCOW - Okunrin ara ilu Rosia (Russia) kan ti oruko re nje Ivan Ivxoy ti o ti ya odi lati nkan bi odun merindinlogun sehin. Gegebi irohin ti a gbo, ise abe (operation) ni dokita na se fun okunrin odi na ki ohun re to la. Nwon ni lati igbati o ti wa lomode ni o ti ya odi

## Baba Gbomogbomo

IJEBU-ODE- A jo Kotu awon o-pa ti fi ejo okunrin kan ti nwon npe oruko re ni Olanrewaju Adenowo ti nwon ni o fe ji omo olomo gbe ni odun ti o koja si Kotu nla (Assizes).

Esun ti awon olopa fi okunrin na sun ni pe ni ojo kan ni idi moto ni oja Oyingbo ni Ijebu - Ode o fi ogbon tan omo kan ti nwon npe ni Kamaru Yiuusa, omo odun meji, lo ki onimoto kan to kigbe mo lori, eleyi lo je ko ju omo na sile.

Odaran na ni iro ni nwon pa mo on. O ni nse ni on ba omo ba omo na sere, on on ko fe jigbe rara. O ni omolangidi ti o nfi sere ni o bo lowo re ki o to ma sokun.

**E KA Iwe Irohin ELTI-OFE**

Mallam Shewu So..

# Irohin Ipinle Ariwa

## Gomina Nile'gbimo

Ipinlẹ Ijọba Ariwa ni Oke-Ọya paapa ṣẹṣẹ ngun oke agba nitoripe nkan ti Gomina enia-dudu (Ọlọla Kashim Ibrahim) ọmọ ilu awọn Kanike ni Meiduga-ri, ti nwọn ṣẹṣẹ gbe sori aga ṣe, ko ti si enia-dudu ọmọ Ipinlẹ Ariwa ti o ṣe iru rẹ ni ile igbimọ awọn aṣofin na ri. On ni gomina enia dudu l'Oke-Ọya ti o kọ sọ fun awọn ikọ ile igbimọ na bi Ijọba wọn yio ṣe nawo ni ọdun ti a fẹ bọ si yi.

### Ise L'Eko

Gomina na ni ki awọn ọmọ ilu on maṣe bẹru ra-ra nipa iṣẹ nitoripe gbo-gbo wọn ni Ijọba awọn yio ba wa iṣẹ l'Eko. O ni awọn yio si ma fun awọn ara ilu ni ẹbun ilewe ọfẹ si, ki awọn ọmọ awọn le tete wa dopo iṣe Ijọba mu dipo awọn alejo diẹ ti nwọn mba awọn ṣe iṣẹ na lọdọ awọn nisisiyi. Gomina na ṣe alaye wipe awọn ni lati ri wipe awọn ọmọ Ipinlẹ Ariwa lo nṣe iṣẹ Ijọba Ariwa laipẹ yi.

### Ile Ise

Gomina Kashim ni Ijọ-ba awọn ti bẹrẹsi da ile iṣẹ orişirişi silẹ ni ilu Hausa, eleyi ko ni jẹ ki awọn ọmọ awọn ma wa iṣẹ kiri mọ. O ni ni ibikan ti nwọn npe ni Jema awọn ti da oko igi okun silẹ, nibẹ ni awọn yio ti ma ri nkan lo fun ile-iṣẹ apo igbokun ti awọn fẹ ma ṣe fun awọn ti o nra ẹpa ati nkan bẹbẹ ni Oke Ọya.

Gomina na ni nipa ti eto ẹkọ awọn ko fẹ ki ọmọ awọn lọ sẹhin tara, o ni awọn ti ri ẹ morinlelogo-sao awọn ọdọmọkunrin ni Ipinlẹ Ariwa ti nwọn yio wọ ilewe giga julo ti awọn ṣẹṣẹ da silẹ ni Zaria.

### Ilewe Madaru

Awọn baba eleto nkan ti o jẹ mọ ile-ẹkọ ni Oke Ọya nibi ti gbe agogo jade lati ṣe ikilọ fun awọn olukọ oniwe madaru ti Ijọba ko lọwọ si wipe awọn ko gbọ-dọ gbọ wipe enikan ko awọn ọmọ ti o kọja mẹwa jọ nile lati ma kọ wọn lẹkọ, afi ti o ba jẹ wipe awọn Ijọba ti fọwọ si iwe-aṣẹ fun oluwa rẹ.

Irohin ti a gbọ nipa awọn ilewe madaru na ni wipe iru wọn bẹ pọ ni adugbo kan ti wọn npe ni Fegge nibi yi.

### Lagido Kano

Awọn Olotu Ijọba Ipin-lẹ yi ti ko awọn orişirişi ọbọ-lagido pamọ si ile kan ti nwọn mbọ wọn ni orişi-rişi ọnjẹ lati fi nwọn ranṣẹ si ilu Oyinbo. Ọdunrun lagido ni ọwọ awọn ti o nmu wọn kakiri inu igbo tẹ nis siyi.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

Awọn Iwe Asiko:

## Ede Yoruba Dun Ka

(Lati ọwọ AKỌWE)

Awọn agbalagba ni ilẹ Yoruba ni nwọn ma npa owe wipe ONIGBA ni pe igba rẹ ni akilaya ti a fi ba a fi ko ilẹ. Itumọ owe yi ni pe bi enia ba ni nkan ti o dara ti ko ba mọlọ lo, awọn eni-ẹlẹni a ma ba a lo o ni ilokulo.

### Ede Elede

Ede awa Yoruba dun ka pupọ ṣugbọn o ma njẹ nkan iyanu fun mi ti mo ba pade awọn kan ninu awọn ọmọ Yoruba ti nwọn ba nsọ wipe awọn ko le ka ede na mọ ayafi ede ilu ajoji bi ti Gẹsi. Eyi ni o mu mi niran nkan bi ogoji ọdun sẹhinnigbati temi pẹlu awọn ọrẹ mi mẹta k n jọ nṣere ni ilu wa.

Ile iwe ni a şi nlọ lọjọ na lọhun; a ṣe alabapade awọn Oyinbo ojişẹ Ọlọrun meji kan ti orukọ wọn njẹ Dokita Green ati Dokita Lockett. Nigbati a ri wọn, o wu wa pupọ lati ba wọn sọrọ l'ede Gẹsi nitoripe a fẹ fi han wọn wipe awa na mọ iwe, a si ti gbọ ede ilẹ wọn daradara. Ede Gẹsi ti a gbọ nigbana ko ju gbedegbẹyọ ti a kọ ninu iwe ologbe (Tişa) J G Kuyẹ lọ.

### Yoruba Atata

Nitotọ, a ju f'ọpa wọn ede Gẹsi si awọn Oyinbo mejeji na, ṣugbọn oju ti wa pupọ nigbati nwọn fi ede Yoruba atata da wa lohun. Inuwa wa dun pupọ lati ba wọn tẹnu bọrọ lorişirişi.

Eyi wa jẹki temi pẹlu awọn ọrẹ mi ṣe ipinu wi-pe a ko ni ko iyan ede ilẹ baba wa kere mọ lati ọjọ na lọ nitoripe onigba ni pe igba rẹ ni akilaya ti a fi ba a fi ko ilẹ.

Diẹ ninu awọn iwe asiko ti a ri gba lati ọdọ awọn oniwe (authors) ni awọn kan ti awọn ọkawe wa ti ntọka si wipe Alufa (Rev.) E A Atilade kọ, ti nwọn ni o kọ awọn ọmọde lọgbọn. Nigbati emi AKỌWE ka wọn mo ri wipe o kọ awa agbalagba lọgbọn, paapa ni aiye ode isişiyi ti a wa yi, ti aiye na ka ẹsẹ kan nilẹ ti o ku ẹsẹ kan, ọkan ti o ku na ko

(Wo iyoku loju ewe kẹfa)

## Oba Obinrin



Aworan yi ni ti Alaiyeluwa Elizabeth Keji Ọbabinriati ilu Gẹsi ti o wa ni irin ajo nisisiyi ni ilu kan ti nwon npẹ ni New Zealand. On ati ọkọ re lo lọ. Ninu Irin ajo wọn na nwọn lo si orişişi lu ti o wa ni New Zẹaland gbogbo awọn enia ni nwọn si gba wọn tayọ-tayọ ni gbogbo ibiti nwọn gbe de.

# ELETI—OFE

A NJUWỌN KO ... WI ...ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS C/BLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 860 SATURDAY MAR 16th-MARCH 22th 193


# ENI TI O BA YO

Ninu awọn oniwe irohin ti o nfẹ ire ilu, ti ko fẹ ki iyan mu, ki ebi ma pa ọmọde ati agba; ti o fẹ ki ẹniti o ti ri jẹ ki o ma pada di atọrọjẹ, ẹniti ko ti ri jẹ ki olodumare ko pese fun un, awa Eleti-Ọfẹ jẹ ọkan ninu awọn ti o nfẹ ilu ire na.

# Ni O Nla Obe

Nkan ti o jẹ ki a sọ wipe ẸNITI o BA YO NI LA ỌBẸ ninu iwe ti a fi ṣe Olori ọrọ wa ọsẹ yi ni ọpọlọpọ ọrọ ikilọ ti a gbọ lati ọdọ awọn enia wa, ati orişirişi iwe ti a ti ri gba lati ọdọ awọn ọkawe wa nipa owo goboyi kan ti awọn alakoso Ijọba Apapọṣe ilẹ wa l'Eko sọ wipe awọn fẹ "fi ta tetẹ ere ẹṣẹ jija" nitori ti awọn ara ilu okere l'Oke-Okun le mọ wipe awa na wa nibẹ

Nwọn ni ẹniti o ba nṣe gegele pe ki nwọn ko ri on larin ẹgbẹ ni nwọn ki saba ri mọ, bẹ ẹniti o ba nṣe bi o ti mọ ki tẹ bọrọbọrọ.

Nkan ti o nṣe wa nisisiyi ni ile yi ju eyi ti a le mọ fi owo goboyi owo awọn ara ilu, ta tetẹ lọ. Ni ọdọdun ni ẹgbẹgbẹrun awọn ọmọ wa lọkunrin ati lobinrin njade ni ile-ekọ ti nwọn ko ri ibi işẹ kan gba. Awọn miran si tun kun igberiko ni ileto wọn ti nwọn nkawọ gbenu lọgọjumọ lori a ri nkan ṣe nkan. Agbara okun'nu wa fun wọn, şugbọn ko si owo lọwọ wọn rara lati lo lori nkan ọgbin ti nwọn gbin soko.

Ni igberiko mi nwọn ko ni Kanga omi mimu rara; omi sobia ni gbogbo wọn mu tọmọ tọmọ, o si nko orisirisi arun ba wọn. Kini o ṣe ti a ko le lo owo ribiribi bayi fun anfani ilu wa, a fi ki a ma fita tẹtẹ.

Lana a gbọ wipe ẹgbawa pọnun (£20,000) ni Ijọba Apapọṣe fọwọ sọ'ya wipe on a ri ko silẹ, loni Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ni awọn na yio fi ẹdẹgbajọ p ọ n u n (£15,000) ṣe atilẹhin fun ere ọjọ kan ṣoṣo ti a fẹ ṣe bi egungun. Nkan ti o de lode, Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun paapa ko ba ti sọ wipe awọn na fẹ da ninu AJỌ-A-DA-KO yi.

Ẹ jọwọ, ẹ ba wa ro ọrọ na, nitoripe ẸNITI O BA YO NI O NLA ỌBẸ.

# Iwe Si Olotu

## Ile Ni A Nwo - - -

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe yin Eleti-Ọfẹ lati tọka si aşişe kan ti awọn oniwe irohin ile wa fẹ ti awọn alamojuto Ijọba ilẹ wa'şe nipa ọrọ ere ẹleşẹ (boxing tournament) ti nwọn fẹ fi na owo goboyi le lori.

Kilo şe ti ẹnyin oniwe irohin ko le ba awọn Olotu Ijọba na da imọran ki nwọn lo owo wa sọna ti o tọ? Dipo ki nwọn ma na owo lori nkan ọgbin ilu wa ki ebi ye pa wa nşe ni nwọn nlu owo na ni ponpa lori nkan ti ko ni şe wa ni anfani.

Awọn ara Amerika ti sọ otitọ ọrọ fun wa wipe a ko ni owo lọwọ rara, a njarunpa lasan ni. Bi ile ba ti ri ni a nwo ki to s'ọmọ ẹni lorukọ.

Emi ni,
Joseph Ọladunjoye
Mushin



Aworan okan ninu awon Olopa elesin ilu Oyinbo nie nwo yi. Ni ilu Oyinbo bi nwon ti ni awon olopa ti o je wipe ese won ni nwon nfi nse ise, beni nwon ni awonti nwon nlo moto lati ma wa awon arufin kiri pelu awon ti o tun je wipe aja ni nwon nlo.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## (Lati Owo Ayiluka)

### 'Lakun Lo!

Ni oni ọjọ abamẹta ti ẹnyin onigbagbọ npe ni Sati-de ni nwọn yio sinku Eni-ọwọ Adelakun Williamson Howells, alufa-agba (bisọbu) ijọ awọn C M S ti o jaJaisi ni ọsẹ ti o kọja. Mo ti mọ 'Lakun tipẹ nigbati o nṣe iṣẹ tiṣa (olukoni) ni Abẹokuta labẹ ("Dawodu") ologbe Alufa (Rev) Oludọtun Ransome Kuti.

Mo si tun mọ ẹgbọn rẹ, Charles, ẹniti gbogbo awọn enia ati awa oniwe irohin mọ orukọ rẹ ni CHARLES BISHOP.. Oloye kan ni ni Abẹokuta, o si ti sọ fun awọn oniwe irohin pe ki nwọn sọ fun awọn sọbọsọla pe ki nwọn joko wọn jẹjẹ loni, ki nwọn maṣe ta felefele ni itẹ ni Ikoyi.

O dun mi lati ri i pe ṣiṣẹ-ntẹle e ni Bisọbu Howells ati on ati ọrẹ rẹ, Oloye W. H. Biney ("Balẹ yaba" ẹmi ni mo fun un loye yẹn nitoripe o jẹ ọkan ninu awọn ti o kọ mu'le si Yaba nigbati awọn ara Eko ni awọn ko ni ba awọn aṣiwere gbe Yaba lọdun ti o ti pẹ) jọ ṣe ọrọ na, ṣugbọn mo ro wipe nwọn ko ni gbagbe ajọṣe ti wọn jọ ma nṣe laiye nitoripe adura awọn onigbagbọ kan ni "bi nwọn ti nṣe laiye bẹni nwọn nṣe lọrun."

Adelakun ọruu re o! Ara Ikija, ọmọ Lisabi.

### Shitta Bey

Ni aiye Eko atijọ a ngbọ orukọ agbo ile Animashaun, agbo-ile Shitta, agbo-ile Sab agbo-ile Akanni, ṣugbọn gbogbo awọn orukọ agbo-il bẹẹ ṣe nṣidi lọ sibo miran bi Eko-tuntun, Mushin, -oro, Oju-owoye tabi ọna Iṣaga.

Irohin ti mo gbọ ni ọsẹ ti o kọja nipa awọn ra agbo-ile Shitta leti ita Balogun l'Eko nibi jẹki inu mi dun pupọju lati ṣe ipinnu wipe ma ṣe ana wọn. Mo gbọ wipe awọn Oyinbo ti o ngba ile (LEDB) ni igboro Eko ti kọwe si Baba Sulu (baba Loya Ramm Shitta) ti o ku ni olori ninu agbo ile na wipe awọn yio san ẹgba mejidinladọta pọnun (£96,000) fun gbogbo agbo-ile wọn ti nwọn fẹ gba-Mọsalasi yẹn k si bẹ o.

Lọya Shitta, ẹjọwọ emi Ayiluka paapa fẹ f'ara mọ yin o! Ki ẹ ba mi wa ẹnikan ninu awọn "ILEMOSU" ọmọ yin obinrin ti o ba ni iwa ti iya ọkọ ba nje ki nma ṣe ikẹ rẹ boya mo le ri ninu owo gọbọy. tabi ẹ ko fẹ pin alejo rara ninu rẹ?

### Omo-Lere

Awọn Yoruba ni ọmọ ko layọ le, ẹni ọmọ ba sin lo b'ọmọ, boya iru ọrọ bayi ni o jẹki Ọgbẹni Tesi Elias, tiṣe alamojuto eto ofin Ijọba Apapọse sọ wipe on fẹ gbe ofin tuntun kan jade fun awọn ọmọ ti nwọn ko ba ni baba, ti nwọn gbe sọnu nigba gbogbo le ma ri baba ti yio ra wọn fi sọmọ (child adoption) gẹgẹbi nwọn ti nṣe ni ilu Oyinbo.

Boya ẹ gbagbe ọmọ kan ti nwọn sonu si ile-idalẹnu ita Faji ni ijọsi, ti ọkan ninu awọn ọmọ wa gbe ti o fi ṣe MORẸNIKEJI ọmọ t'obi. O ti ran an lọ si ilu Oyinbo, ọmọbinrin na si ti di enia atata nisisiyi ni ilu yi.

Tẹsi, Oluwa ko fun ẹ ṣe ki a le ri ọpọlọpọ ọmọ gbe ṣere.

### 'Tokunbo

Ọrọ ọmọ ti mo nsọ yi lo jẹ ki nniran arabinrin wa kan, Wolimọtu, iyawo Ọgbẹni Alex Oni ti o ṣẹṣẹ bi ọmọkunrin kan jantojanto ni ijejọ lehinti on pẹlu bale rẹ ti ilu Oyinbo de. Awa Eleti-Ọfẹ sọ ọmọ na ni ADETOKUNBỌ. Ọlọrun ko da a si. Mo gbọ wipe iyawo Ọgbẹni Taju Animashaun paapa bi ọmọ tuntun ati pe loni ni nwọn yio ko gbogbo wọn jade.

Adura emi Ayiluka ni pe ki Ọlọrun ki o ṣe awọn ọmọ na ni alalubarika ṣugbọn ki ẹnyin baba awọn ọmọ na ma gbagbe ọti biya (beer) ikomọjadẹ temi na o.


Plug in to a
BRIGHTER
FUTURE . . .



**And the best way of doing this is to take a life Insurance policy fo yourself and children from those who are ready to help:**

**Great Nigeria Insurance Co. Ltd**

(Incorporated in Nigeria)
Head Office: 39/41 MARTINS STREET, LAGOS.
P. O. Box 2314, Tel. 25251
Branches:- WRFC Building Lebanon Street, Ibadan;
151A, Folagbade Street, P. O. Box 133, Ijebu-Ode;
Telephone 82 Ibara Road Abeokuta.



## Akiyesi

Gbogbo eniati nwon nwa ogbon ni nwon nka iwe irohin Eleti-Ofe. Iwo na ma ka a ni osose; o kun fun irohin ile Nigeria ati Oke-Okun.

# Iorhin Ipinle Ariwa

## Gbanjo Ile Oba

Ko si ibiti ese ko si o fẹre da bi eni wipe ti ile awọn kan ni o peleke. Ọrọ ile kan ti Ọba Zaria, Alhaji Muhammadu Aminu kọ ti o fẹ ta ni ẹdẹgbari . ponnn (£7,000) fun Ijoba Ibilẹ Zaria fẹ bẹge bi adubi. Nwọn ti se gbogbo iwe ti ọwọn yio san lori ile na tan ki Alhaji Othman Ladan tiṣe Komisanna alamojuto ilu Zaria tọ kese bọ wipe ki nwọn da a duro, ki nwọn mā ti san owo na rara nitoripe ko tọna.

Mo gbọ wipe owo Ijoba pelu awọn ẹlẹwọn ọba ni nwọn mu fi ko ile na.

## Ni Zaria

Posu ọfisi (ile ifiwe ranṣẹ) tuntun ti nwọn fi owo nibiribi kan kọ ni nwọn sese si ni Zaria laipẹ yi. Ọgbeni Olu Akinfosilẹ tiṣe Minisita alamojuto eto ifiwe ranṣẹ ni o ṣi ile tuntun na. O ni idaji gbogbo owo ti awọn nri lọdodun lori ilosiwaju Ipinlẹ Ariwa ni awọn olotu Ijọba Apapọṣe nlo owo na si.

Eleyi je esi ti o fi si ọrọ kan ti Alhaji Usman Ladan Bak, Komiṣana Zaria, sọ wipe nwọn ko tọju awọn te ni Oke Ọya.

Ọga-agba ilewe giga julọ, Ahmadu Bello University, ti nwọn sese da silẹ ni ilu Zaria ti fi ive s'ode wipe awọn le fun enikeni ti o ba kọwe yege lọdọ awọn ninu iṣẹ itọju ilu (Public Administration) fun ọdun meta gbako ove kan ti nwọn npe ni B.A. pelu iwe-eri ni awọn yio fun Oluware. Otun ṣe alaye wipe ninu oṣu October ni ọdun ti mbọ ni awọn yio gba awọn kan.

## Ilorin

Adajọ agba Kotu awọn Ọlọpa, Ọgbeni Shams-Ul-Haque ti sun ẹjọ arufin kan, Godson Ogbonisiegbe, akọwe ibiti nwọn gbe ti ngba enin ṣiṣẹ ti awọn ọlọpa mu fun esun wipe o pa iyawo rẹ, siwaju nwọn si ti mu arufin na lọ si ọgba ẹwọn Ilorin fun ipamọ.

Ẹsun ti awọn ọlọpa ka si i lẹsẹ ni wipe ninu oṣu Januari ti o kọja yi ni ago meje owurọ kutukutu ni Ago awọn akọwe Ọba ni opopo Lafiagi ni Ilorin, Arufin yi pa iyawo rẹ ti o nje Juliana.

Nwọn ni ẹṣẹ ni o ṣa obinrin ti o nlọ ọmọ lọwọ lọgbẹ, ti o si pa a bamu bamu.

## Oba Tapa

Ọba Tapa tuntun ti o ṣẹṣẹ jẹ, Alhaji Usman Sarki, se idajọ lori awọn Tapa apeja kan ti nwọn ni nwọn lọ si odo olodo lọ pa eja ni ilu ti nwọn npe ni Katcha. Adorin ọdun ni wọn O ni ki awọn mọkandinlogoji san oke mewa sile enikọkan. Gomani Yesufu, Olori wọn fi ponun marun tan ran.

Ọba na ri ki nwọn si tun fowo bọ iwe wipe nwọn ko ni fa ijongbọn rara fun ọdun kan gbako, ki nwọn si san adọta ponun sarai fun eniti o ni ọgọdọ omi ti nwọn lọ pa eja nibẹ.

Gbogbo owo ti nwọn fi tan ọran na jẹ ponun mejilelogọsan (£182). Ọba na tun se ikilọ fun gbogbo awọn ti o wa ni kotu pe on ko fẹ ija rara.

## Ede Yoruba Dunka

(Oberẹ loju ewe keta)

ile to ile mọ . . . —

Ni aiye ti a wa yi ofin Ijọba ti de obi mọlẹ ko gbọdọ mu ẹgba ki o na ọmọ ti o bi, ambọ-tori tiṣa alagbatọ kan. Awa agbalagba paapa a ko ri eni sọrọ ko-ba-kun-gbe to fun wa rara, sugbọn mo bẹ enyin ọkawe mi, e lọ ka iwe Alufa Atilade; iwe na sọrọ fun ni ju ẹnu lọ.

### Tani Atilade ?

Boya ẹ le bere wipe tani Alufa Atilade ti o kọ awọn iwe na. Eniọwọ Alufa (Rev) E.A. Atilade ti o kọ awọn iwe bi AKOKA YORUBA (apa kinni de apa kefa), IRIN AJO OPALABA (apa kinni ati ikeji ( ti nwọn nfi igba kan ka ninu ero redio lojojumọ) ati awọn IWE IKILỌ fun awọn ODỌ (apa kinni de ikarun) ni Alufa ajihinrere ijọ Ṣọsi Gospel Baptist l'Eko ati agbegbe re.

Olukọni pataki ni Alufa Atilade, o to ọdun mọkanlelọgbọn nisisiyi (nigbati o ti nkọ wọn lẹkọ ninu ile iwe giga ni Baptist Girls' High School, Idi - Aba, Abẹokuta) ni o ti nṣe akinkanju lati ṣe iwe kika fun awọn ọmọ ilewe ilẹ wa. Awọn ẹlomiran jẹ awọn ti a fun ni ẹbun olukọni wa lati ọrun; Alufa Atilade jẹ ọkan ninu iru awọn enia bẹ.

Ki i ṣe ifẹ owo ni o ndamu rẹ ki o to da ile-ẹkọ silẹ fun awọn ọmọ wa, sugbọn ifẹ ki olukulu awọn ọmọ wa ti nwọn ko ri ile-ẹkọ lọ le ni anfani ẹkọ ni.

Ni agbara Oluwa, ni ọsẹ ti mbọ ma da die fun yin ninu IWE IKILỌ Fun Awọn ODỌ ti Alufa Atilade ṣeṣẹ te jade ; nibe ẹ o ri wipe iwe na sọrọ fun wa ju ẹnu lọ, o si kọ wa lọgbọn pupọ. Bi o ba jẹ onigbagbọ o le fi ọrọ inu iwe na ṣe iwasu ninu Ṣọsi, bi o ba si jẹ Alufa Arọwasi o le fi ọrọ inu rẹ rọ wasi ni iwaju awọn janmọ rẹ ni Mọṣalaṣi.

( Iyoku di ọsẹ ti mbọ )



Aworan Ogbeni Dave Charnley, Oyinbo Gesi kan a bese-ku-bi-ojo ti o je olori awon eiese kan ni ilu Oyinbo ni e nwo yi nibiti o gbe ti ngba ara ilu Amerinka kan ti o nje Jethro Cason lese ni ibiti nwon gbe ti ser ese jija laipe yi ni ilu London. Ogbeni Charnley na lo bori

# British Scientist To Work On Nutrition In Nigeria

LONDON— A British expert in agricultural chemistry will be arriving in Lagos this week by sea to work at Moor Plantation near Ibadan.

He is Mr. Anthony Robert Bromfield, M. Sc., who is to spend three years in laborarory and field work on plant nutrition, under the Nigeria/U K. technical assistance arrangements.

Mr. Bromfield was for two years a lecturer in agricultural chemistry at the Royal Agricultural College, Cirencester, Gloucestershire. He took his M.Sc. at the Univearsity of Birmingham.




Detective Inspector Rupert R. Bushell (right) listens to a Tanganyikan school-teacher, Mr. John Mbenna, describing the school in Dar es Salaam where he used to teach. This picture was taken in the offices of the British Council in Birmingham where Mr. Bushell has been a member of the city police for 25 years. In April he will sail for Tanganyika to become assistant superintendent of police in Dar es Salaam


**DAGENITE**

BATTERIES

*give you a longer run for your money!*




SOLE AGENTS & DISTRIBUTOR FOR NIGERIA

**LEVENTIS MOTORS LTD**

LAGOS. APAPA. IBADAN. KADUNA. KANO. JOS. PORT—HARCOURT. ABA.


## Belfast Nurse For Nigeria

LONDON — A life-long ambition to work as maeyternitnurse in Africa has come true for a 24-years old Belfast, Northern Ireland, girl, now on her way to Nigeria.

Miss Renee Hughes a staff nurse at Belfast City Hospital, is joining St. Mary's Missionary Hospital, Urua Akpan, for the next two vears.

## The "Ahmadu Bello" Launched In Britain

LONDON—Nigeria's new cargo liner, built in north-east England for the Nigerian National Line Ltd., was launched at the Neptune yard of Swan Hunter and Wigham Richardson Ltd., of Wallsend, Northumberland, yesterday afternoon.

She was named "Ahmadu Bello" by Mrs. K. K. Balogun, wife of the Chairman of Nigerian National Line, who deputised for Mrs. R.A. Mjoku, wife of the Federal Minister of Transport and Aviation, who was unably to be present through illness

Mr. E. J. Hunter, chairman of the builders said at a reception after the launching: "It is a great satisfaction for us to build ships for our Nigerian friends."

The "Ahmadu Bello" is a sister ship of the Nnamdi Azikiwe," built at the same yard and launched last October.

She has five cargo holds deep tanks for oils or latex, single cabins for each member of the crew and accommodation for 12 passengers.

## African Historian To Advise At University Of Nigeria

LONDON -- An educationist and authority on African history, Dr. John Edgar Flint, has been invited under Nigeria/U K. technical assistance arrangements to help in the development of the African history programme at the University of Nigeria Nsukka.

## Baba Onisegun Pokunso L'Ebute—Metta

Ebute—Mẹtta — Ẹni ya gbogbo awọn alaisan ti o wa si ile Alufa Ọlọruukẹmi Arikewuyọ ni Ebute—Mẹtta ni owurọ ana lati gba egbogi lọwọ rẹ ti nwọn ri ni iyara nibiti o gbe pokunso si.

Irohin ti a gbọ nipa onişegun na ni pe akankan kọ şe e rara lọjọ na, o si ti gbe awọn agbo ti o fẹ lo fun awọn alaisan lọjọ na ka'na ki o to wọ inu yara rẹ tilẹkun mọri ti o fi okun bọ ọrun, ti o nrọ diro—diro.

Bi ko ba si ti aburo rẹ ọkunrin ni nwọn ko ba fi fura si i pe o ti ku si inu ile na.

## Karimu Adamu Di Omo Orukan

Anu şe wa lati gbọ iku iya Ọgbẹni Abudu Karimu Adam ti o jalais ni Eko ni ana Ẹni ọdun marundinladọrin ni iya ti o jalaisi na, nwọn si ti sin gẹgẹbi nwọn ti nsin oku awọn Imale.

Ọlọrun ki o fi ọrun kẹ.


RECORDS OF THE WEEK

78 R.P.M. at 7/- each
P 82462 H
Me Begyaa Mo/Otan Be-brebe Yi
P 82461 H
Oba Dziseefo/Odeyewu
Bra E. K.'s Band
P 82482 H
Nsa Fufuo/M'ahoma Tea
Casino Dance Band
45 R P M at 6/9 each.
P 382370 F
Kelewele/Anyi Di
Eddy Okonta and his Jofabro Star Aces
P 382305 F
Esura/Alamisi
Adeolu and his Rio Lindo Orchestra.

PHILIPS
of course...
—the records of the century—
Philips (Nigeria) Ltd.
Head Office: PMB 1136
Apapa
Branch Office: P.O. Box 429
Ibadan


## E Ka

**Iwe Irohin Eleti—Ofe Ti O Kun Fun Irohin Aladun Ati Ogbon Lo-sose**


## LAGOS RACE CLUB

EASTER MEETING, 1963.
SATURDAY 6th 13th MONDAY 15th. SATURDAYS 20th & 27th, APRIL, 1963.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, PO. Box 51, Lagos or at the Race Coarse, Lagos.

Note—No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 25th March, 1963.

No Cheque will be accepted.

C.H.E. MILLER
Hon. Secretary.


# Awon Olopa Nmu Enahoro Bo Wa S'Eko

LONDON—Oloye Anthony Enahoro ti awọn ọlọpa ti fi igba kan wipe awọn uwa fun ẹjọ ọlọtẹ ti nwọn mba awọn Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ şe ni a gbọ wipe awọn alaşẹ Ijọba ilu Gẹsi ti sọ wipe ki nwọn da a pada si Eko, awọn ko le gba laye ki o joko si ilu Oyinbo.

O to oşu mẹta nisisiyi ti Oloye Enahoro gunlẹ si ilu Oyinbo (London) lati ilu Ghana nibi ti o ti lọ sa pamọ si lati nkan bi oşu mẹfa sẹhin ti rogbodiyan ti bẹ silẹ ni Ibadan ni on ati Dokita Chike Obi ti mura gba ọna Idiroko lati sa lọ si Ghana ọwọ awọn ọlọpa tẹ Dokita Obi, şugbọn Oloye Enahoro salọ mọ wọn lọwọ.

Ni ilu Oyinbo, Oloye Enahoro ja ajabọ titi şugbọn ko bọ si. O kọ iwe-ẹbẹ si awọn alaşẹ ilu Gẹsi wipe ki nwọn jọwọ ki nwọn ma fi on ranşẹ si ilu Nigeria ki nwọn dabo bo on gẹgẹ bi oşelu ti o sa wa ba wọn.

Nwọn fi ọrọ na logun, nwọn fi lọgbọn, nwọn ni ki nwọn sa mọ mu Enahoro lọ si ilẹ Nigeria ni awọn fọwọ si

Boya awọn ọlọpa ti o lọ mu wa le gunlẹ si Ikẹja loni pẹlu Enahoro na.

## Awon Olopa Mba Dokita Otegbeye Se'jo

(Obẹrẹ loju ewe kini)

Awọn Ọlọpa sọ fun aaajọ wipe ki o ba awọn sun ẹjọ na siwaju ki awọn le gbaradi lati ro ẹjọ na; nwọn si ti fi ọjọ ẹjọ na si Tuesday ọjọ marun loni.


YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE (NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA.
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company,28,Kosọkọ Street LagosBox 467 Phone 23370 Editor, (Olotu)Ọla Ọnatade, 15,Kosọkọ Street, Lagos.